**Lakaye Ọrọ**

NIGBANA ni mo wo gbogbo işẹ Ọlọrun, pe enia ko le ridi işẹ ti a nşe labẹ ọrun nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ, sibẹsibẹ ki yio le ri I, ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọn enia re lati wadi rẹ, sibẹ ki yio le ridi rẹ.



# Irohin Yoruba

NO. 383. May 24 — May 30, 1961 KOBO MEJI (2D)




O dara pupọ fun Ikọ ti o nyọ awọn ẹbi rẹ lẹnu

O wa fun tita kakiri Ile-ẹgbogi

# MUSULUMI Ẹ KU EWU ỌDUN

NI ọpọlọpọ isu ti awọn Musulumi wa ni nwọn ti nşe ipalẹmọ Ọdun Ileya silẹ lati nkan bi oşu kẹta sẹhin, nwọn nfi owo ti nwọn yo fi ra ẹran agbo pamọ. Ẹran na ni nwọn yio fi jọsin fun Ọlọrun ni ọjọ ọdun na.

Ni alẹ oni ni nwọn yio si şe aisun ọdun na nigbogbo ibiti Musulumi wa. Ẹlomiran yio şe aisun na'ni adugbo, nwọn yio jẹ nwọn yio si mu ọti amupara, nwọn yio si ma a jo, nwọn yio si ma a yọ. Imọ awọn wonyi nipa Ẹsin Islam ko jinlẹ. Awọn ti o ni imọ ijinlẹ nipa rẹ yio lọ şe aisun ni moşalaşi adugbo wọn. Nibẹ ni nwọn yio ma a yin Ọlọrun logo, nwọn yio si ma a fi orukọ Anabi Muhammed (ki ikẹ ati ọla ma a ba A titi lailai) tọrọ gbogbo ire ti nwọn ba nfẹ lọdọ Ọlọrun.

Ni ọjọ Ọdun ti awọn Musulumi yio şe lola ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kẹdogbọn oşu yi gbogbo wọn yio şe ẹsọ lọ Moşalaşi Ọdun l'arọ. Lẹmọmu Agba yio si yan nọfila fun wọn pọ. Lẹhinna ni yio si pa malu fi jọsin si Ọlọrun. Lẹhin eyi olukuluku yio pada si ile rẹ yio si pa ẹran agbo rẹ fi jọsin fun Ọlọrun. Nwọn yio si ma a jẹ ma a yọ.

(Wo oju ewe kejila)



Awọn Alhujaj njọsin fun Ọlọrun




AWORAN ile yi ni Banki ti Ijọba Apapọ Naijiria fẹ şe iwadi nipa rẹ.

## Ijọba Apapọ Naijiria fẹ wadi nipa banki Ijọba Iwọ-Orun

IJỌBA Apapọ Najiria ti yan ikọ-iwadi kan lati wadi işẹ gbogbo to jẹmọ Ile-ifowopamọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti a npe ni National Bank.

Ikede to jade lati ile-işẹ Igbimọ Alaşẹ Ijọba Apapọ Naijiria lọşẹ to kọja sọ pe Ọlọla Vahe Bairamain, ọkan ninu awọn adajọagba ti Kotu Apapọ Naijiria ni yio şe iwadi na. Ohun ti Ọlọla na yio wadi ni:

Ekini: Gbogbo Işẹ Banki na ati eto inawo rẹ ati ti awọn ẹka rẹ gbogbo lati ibẹrẹ oşu kẹwa ọdun 1959 titi de ipari oşu kejila oşu ọdun 1960.

Ekeji: Ọna ti Banki na fi nya awọn enia lowo; iye owo to nya wọn ati anfani to pese fun awọn enia lati ya owo; ati bi ohun ti nwọn fi duro lati ya owo ba fẹsẹmulẹ tabi o to eyiti o yẹ lati fi ya owo, ati iye owo ti Banki na ya awọn ẹka rẹ tabi awọn alabojuto rẹ tabi ẹbi awọn alabojuto rẹ: işẹ tabi ẹgbẹ to da işe silẹ ninu eyiti alabojuto Banki na ni ọwọ.

Ẹkẹta: Ibatan ati ibaşe Banki na pẹlu awọn alabojuto rẹ; Igbimọ to nmojuto tita ọja ni Ipinlẹ Iwọ-Orun; Ẹgbẹ Oşelu tabi ẹgbẹ awọn enia to nşoju fun ẹgbẹ oşelu na.

Ẹkẹrin: Bi işẹ ati ilana Banki na ba şe dede pẹlu ofin Işẹ Banki ni Naijiria.

Ẹkarun: Bi işẹ ati ilana Banki na, ati ohun miran nipa Banki na ko şe dede tabi bi ẹnikẹni ninu alabojuto Banki na ba ti kuna ninu işẹ wọn.

Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Oloye S. L. Akintọla ti sọrọ lori yiyan ikọ-iwadi na. Ninu ọrọ rẹ

(Wo oju ewe kejila)

# Ọlọpa mba awọn mẹta ṣẹjọ ole eku-okete

BENIN.

AWỌN ọlọpa Benin mu ẹsun awọn agbẹ mẹta ti orukọ wọn njẹ Omorodiongu, Igbinova ati Rapheal Omogu wa siwaju Adajọ Kotu Ibilẹ kan ni Benin ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi pe nwọn lọ ji okete tu ninu takute (trap) ti Ọgbẹni Awaguoro Enagboma dẹ sinu oko rẹ.

Awọn agbẹ mẹtẹta na ni awọn ko jẹbi ẹsun na. Okete ti awọn ọlọpa sọ wipe nwọn ji tu loju takute na ko ju ṣile mẹta abọ (3s. 6d,) ti nwọn ba ta a. Adajọ gba iduro wọn lori ponun mẹdọgbọn (£25) pẹlu oniduro kọọkan.

## Ikomọ ọmọ Ọsanyinro dun

OMU-ARAN.

ỌGBẸNI M. O. Ọsanyinro ko ọmọ ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Felicia Ayọdele lọrẹ. Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni o ṣe ikomọ na, o si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun. Aṣeyẹ ọjọ na dun o larinrin, irohin ko to afojuba.

Awọn Ọgbẹni J. O. Suru, J. O. Obaro; J. Ishaiah; P. A. Adewunmi Fadeyi; L. A. Agboọla, J O. Adeoye, F. Titilayọ ati S. O. Fasoyin wa ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na.

## Mutaru Gbeyawo

AGBOJA ẸDẸ.

AṢEYẸ igbeyawo Ọgbẹni Mutari Lawal ati Omidan Mọnyinọla ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi dun o larinrin,

Ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Y. K. Lawal, Y. S. Akanbi ati Surakatu Lawal. Ọlọrun ko fi adun kari o, ko si fun iyawo ni ọmọ rere o.

# Akẹkọ Agba Ijọ Onitẹbọmi ṣe ẹyẹ idagbere fun olukọ wọn

ISIN idagbere ti awọn akẹkọ agba (Adult Class) ti Ijọ Onitẹbọmi Kini, ti o wa ni 'Broad Street, l'Eko ṣe lenulọlọyi fun Iyaafin B. I. Griffin ti iṣe Olukọ agba fun awọn akẹkọ agba nigbati o nlọ si ilu rẹ Amẹrika fun isinmi rinlẹ gidigidi.

Ki isin idagbere na to bẹrẹ ni agogo mẹrin abọ irọlẹ, ẹsẹ gbogbo Ijọ ti pe si Ṣọọṣi. Iyaafin J. I. Ayọrinde ni o ṣe alakoso isin idagbere na. Lẹhin isin na ni Iyaafin B. I. Griffin gba gbogbo awọn akẹkọ agba ni iyanju pe, ki nwọn mura si ẹkọ wọn daada, ki nwọn ma si fi ile-iwe wiwa wọn jafara.

O ni nitootọ, on npada lọ silu on ni Amẹrika pẹlu inu didun nitoripe on yio ni anfani lati foju kan awọn ọmọ ati ẹbi on ti on ti fi silẹ lati ọjọ pipẹ, o ni bi o tilẹ jẹ wipe on fi wọn silẹ gẹgẹbi olukọ wọn, sibẹsibe on ni igbagbọ pe awọn Ọgbẹni Festus Adewuyi ati Joseph Okunlọla olukọ ti o jafafa ti on fi silẹ ni yio ma a kọ wọn ni ẹkọ ti o ye koro, nitoripe nwọn gbọ ede ara wọn.

O ni nisisiyi on nlọ si ilu on, ṣugbọn ki nwọn fi adura sin on, ati wipe idunnu on ni yio ma a jẹ nigbagbogbo ti on ba nri iwe (letter) wọn gba ti on ba de ile.

Kete ti o sọrọ tan ni on, awọn ọmọ ile-iwe ati awọn olukọni jijọ ya fọto, nwọn fun un ni fọto na gẹgẹbi ẹbun iranti.



EYI ni aworan awọn akẹkọ agba ati olukọ wọn.

## Olumẹgbọn ko ọmọ jade

EKO.

LENULỌLỌYI ni Oloye Abudu Lamidi Kalefo Keji, Olumẹgbọn-Ajaye Eko ṣe ikomọ ọmọ ọkunrin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, 'Lẹyẹ Olumẹgbọn lọrẹ, ni Iga rẹ. Lemọmu Saba ni o ṣe isin isọmọloruko, nwọn si sọ ọmọ na ni Lukeman Abiọdun.

Ẹsẹ awọn enia pataki pataki ni o pe si ibi aṣeyẹ na, baba ọmọ na si na'wo fun wọn t'dunnu-t'dunnu lati arọ titi ilẹ ọjọ na fi ṣu. Awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na le ni igba (200) enia.






Mama fi AMAMA kun

onjẹ mi lojojumọ



Lo akanṣe ṣibi pẹlẹbẹ ti o wa ninu pakẹti na fun oṣuwọn bibu iyẹfun Amama.

Da ẹkun ṣibi Amama meji sinu onjẹ ọmọ rẹ

Ma a ṣe eyi ni igba meji lojumọ ni ojojumọ lati ọmọ oṣu mẹfa titi di igbati o ba dagba to lọ si Ile-iwe




AMAMA

NI NAIJIRIA NI A TI ṢE AMAMA

AWỌN ALAGBATA RẸ NI: GLAXO—ALLENBURYS (NIGERIA) LTD.
P.M.B. 2310, LAGOS, ati pẹlu ni ABA ati KANO.

# KADARA ẸDA (20)

## Lati ọwọ M. A. Akinbọade, Ibadan)

OPỌLỌPỌ awọn enia lode oni, paapajulọ, awọn ọmọwe ati akẹkọ, ni o nṣaata awọn awari gbogbo ti awọn akẹkọ ijinlẹ nipa igbesi-aiye ẹda ti ṣe, ati orișiriși akiyesi wọn lati ọgọgọrun ọdun sẹhin. Awọn ọlaju ati ọmọwe ma a nsọ pe, alaye ati ẹkọ ti ko fidimulẹ ti ko si ni koko kan ti o ṣe e dimu ni awọn akẹkọ ijinlẹ wọnyi nfi sode, ti nwọn si nsọ pe, o jẹmọ igbesi-aiye ẹda.

Ṣugbọn akiyesi finifini fihan pe, ohun ti o jẹki awọn ọmọwe ma a sọ bayi ni pe, bi ẹkọ kikọ ti ngbooro si i to ni gbogbo agbaiye, awọn Ijọba ati Alaṣẹ orilẹ-ede gbogbo ko ti i fi asiko silẹ lati ṣe iwadi ati ofintoto awọn ofin iṣẹda gbogbo ti o jẹmọ kadara ẹda.

Iaiṣe aniani, aimoye awọn ọmọwe lo wa ni orilẹ ede gbogbo, ati ni ilẹ awa enia dudu nihinyi ti nwọn ko jẹ ṣai ka iwe irohin kan tabi omiran nitoripe akiyesi awọn Aworawọ wa nibẹ. Oju iwe ti akiyesi awọn Aworawọ wọnyi wa gan an ni iru awọn enia bayi yio kọkọ ma a wa lọ, bi nwọn ba si ti ri i, nwọn o mikanlẹ, nwọn yio si ka eyiti o ba ba Ọjọbi tiwọn mu. Eyi si le jẹ amọran ti o le fi ni mọna ni igbesi-aiye ẹni, tabi ikilọ fun ewu ti o mbọ; o si le ṣai ni itumọ kan pataki fun ẹlomiran. Ṣugbọn o da mi loju ṣakaṣaka pe, igba pupọ ni ọpọlọpọ awọn ẹlomiran ma a nṣẹ ninu asọtẹlẹ awọn amoye wọnyi.

Gẹgẹbi awa na si ti mọ, awọn babanla wa paapa ni ẹkọ ijinlẹ tiwọn, ati ọna tiwọn, lati fi mọ ohun ti o le ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju, ṣugbọn nwọn ko mọwe. Ẹkọ ijinlẹ ti awọn babanla wa wọnyi kọ, ti nwọn si nlo, kun fun ọgbọn ati oye, eyiti o le wulo fun gbogbo ẹda alaye. Ọpọlọpọ ẹkọ ni a le ri kọ ninu itumọ awọn Odu Ifa mẹrindilogun, tabi ninu alaye lori Yanrin titẹ, tabi dida Ẹrindinlogun. Bi o ko si tilẹ ni igbagbọ ninu Asọtẹlẹ,, a o ri anfani ninu ẹkọ ti wọn kọni.

Nigba kan diẹ sẹhin, mo lọ si ọdọ Alagba Babalawo kan, lati fi Imọ ati Ọgbọn ijinlẹ we ara wọn. Mo mu ọkan ninu awọn ohun eelo ti awọn Oyinbo ma a nlo fun iwadi nkan lọwọ, ṣugbọn nko tete fi ara han si baba na. Laipẹ o da Ifa rẹ, o si sọrọ diẹ lori itan awọn ọlọgbọn meji kan ti nwọn pade, ati pe, on tilẹ fura si mi. Nigbayi ni mo jẹwọ fun un, o si tun da Ifa rẹ.

Ni kukuru ṣa a, o mba ọrọ rẹ lọ bayi:—Ọyẹku meji ni Odu ti o jade. Bi Odu yi ba si jade si enia, a o ma a sọ fun oluwarẹ pe, ahun-ṣiṣe ati ọwọ didi ko dara, ibi ni o ma a nmuwa. Nigba laila̩i ọkunrin ọlọrọ kan mbẹ ti o njẹ Alapa—o jẹ Ọba ilu Apa. Nigbati o ṣe, Ọba Alapa fẹ ra ẹru kan, o si lọ ṣe ayẹwo lọdọ Babalawo bi ẹru na yio ṣe on ni ire. Lẹsẹkanna ti babalawo ti da Ifa ni o ti mọ ohun ti Alapa fẹ ṣe ati iye owo ti mbẹ lapo rẹ.

Babalawo wa sọ fun Alapa pe, ẹru ti o fẹ ra lọla yi yio ṣe ọ ni ire pupọ-pupọ, ṣugbọn o nilati fi ṣile mẹta ṣe saraa ninu ọgbọn ṣile ti o mbẹ lọwọ rẹ bi o ṣe joko yi.—Ṣugbọn Ọba Alapa ko fẹ yọ kọbọ ninu ọgbọn ṣile na nitoripe o ro wipe bi on ba yọ ninu rẹ, owo yoku ko ni to lati fi ra ẹru ti o lẹwa daradara ti o si dara lati fi ṣe aya, nitorina, o kọ lati fun babalawo na ni ṣile mẹta yi. Ṣugbọn alagba na, gẹgẹbi ọlọgbọn ati enia ti oye ye pupọ nipa kadara ẹda, ko binu si eyi, o fi Alapa silẹ pe ki o ma a lọ.



M. A. AKINBỌADE

* * *

Ki ilẹ ọjọ keji to mọ, Ogun, ti o jẹ gbẹnagbẹna, ti sare lọ fi igi gbẹ aworan obinrin kan ti o pupa wẹlẹnjẹ, ti o si ni ẹwa pupọ. Lati ọdọ Alujọnnu Ina (Element of fire) ni nwọn ti gba awọ ti wọn fun obinrin na.

Nigbati Ogun gbẹ ere na bayi tan, o gbe e fun Oriṣa lati fun un ni ẹmi, nwọn si gbe e fun Eṣu lati lọ ta a fun Alapa ni ọjọ keji. "A-ri-ma-le e-lọ" ni ẹru-binrin yi jẹ, ṣugbọn Eṣu ko ta a fun ẹnikẹni titi ti Alapa fi de ibẹ, o si ra a ni ọgbọn ṣile. Ẹnikẹni ko ti i ri obinrin ti o dara to bẹ ẹ ri, eyi si mu ki inu Alapa o dun pupọ to bẹ ẹ gẹẹ, ti o fi jẹwipe ni ọjọ na gan an ni o ti fi obinrin na ṣe aya ati aayo rẹ. gbogbo iṣẹju ni o si nlọ fi ọwọ pa a lara. Ni irọlẹ ọjọ yi, obinrin na wẹ, o fi aṣọ daradara si ara, o jẹun o si lọ sun.

Nigbati o di agogo meji oru, Oriṣa gba ẹmi arabinrin na, o si pada si ere Ṣugbọn Alapa ko ti i mọ eyi, nitoripe ọtọtọ ni ibiti nwọn gbe sun. Bi ilẹ ọjọ keji ti mọ, pẹlu igberaga ati ayọ kikun ni Alapa fi wọle lati lọ ki ẹru-binrin ati aya rẹ titun, ṣugbọn ooyi kọ ọ loju nigbati o de ibẹ ti o ba ere lasan. Pẹlu itara, ni o fi ke pe gbogbo ara ile.

Bi o ti nbanujẹ lori eyi lọwọ ni Eṣu de, nigbati Alapa si sọ itan yi fun un: Eṣu sọ fun un pe ki o gbe ere na kọrun ki o si ma a jo yi ilu Apa kakiri. L'aiye igba na, ẹnikẹni ko gbọdọ ba Eṣu jiyan rara, aṣẹ ti o ba pa ni enia lati tẹle. Bayi ni Alapa gbe ere na kọrun, Eṣu si nlu ilu fun un, osi njo yipo ilu Apa larin ẹgbẹgbẹrun awọn ti nwọn woran rẹ pẹlu iyanu nla.

(Wo oju ewe kẹsan)


# Nikehin wayi

## abẹ infarungbọn to mu julọ




## Ọbẹ Alafẹfẹ NACET Ọlọni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD · LAGOS · ABA · KANO

May 24 — May 30, 1967


# AWỌN ARA MUSHIN Ṣ'ỌDUN EEGUN



MUSHIN.

A ṣi i yanilẹnu ri o.



AWORAN yi ni igbati Ẹya'gun gele ohun eegun nje Yagba.

AWORAN yi ni igbati awọn eegun Mushin npidan ni ila ẹya-agan won.


FUN AGBARA



FUN OKUN-INU

FUN AGBARA AWỌN ẸRI

**HOMMEL'S**

**HAEMATOGEN**

ALBAN PHARMACY LIMITED.


## Sonẹkan d'ologbe

ABEOKUTA.



AWORAN isale yi ni ti ọkan ninu awọn eegun Mushin nigbati o nwọra ọdun kakiri igboro Mushin.

## Alapara Ibadan



ALAPARA IBADAN

## Nwoka ku sinu Ṣọọṣi

ONITSHA.

## Ọladipọ gba idajọ iku

EKO.

## Obirin ti nwọn npe lajẹ fẹ pa ara rẹ

IBADAN.


WO IKỌ FEE SAN

Sun un bi ọmọde

## Ẹ ma a rin irin-ajo ni Irọrun



£33-10-0



TECHNICAL DEPARTMENT

34, MARINA LAGOS

# Ẹ FIYESILẸ...

### LATI ỌWỌ MAṢEKẸGANMI

Ki i ṣe temi lati sọ pe ewu mbẹ nibiti ewu ko si. Ki i ṣe temi lati fi imọlẹ pe okunkun tabi lati fi ọrẹ han bi ọta. Ki i ṣe temi lati pẹgan tabi ṣata ẹnikẹni ninu awọn ti Ọlọrun ati ifẹ awọn enia fi si ipo "agbara ijọba aiye yi ati gbogbo ogo rẹ."

Ṣugbọn temi ni, o si yẹ ki o jẹ ti gbogbo awọn to ba fẹ alafia ati iṣọkan Naijiria, lati mọ ohun ti i ṣe alafia ati ifọkanbalẹ mi.

Temi ni, o si yẹ ki o jẹ tirẹ ati ti gbogbo wa lati jẹki imọlẹ otitọ mọ si awọn oṣelu wa, paapa "awọn to njẹ enia bi onjẹ", sibẹ ti nwọn nkede iṣọkan Naijiria. Nitorina, ọrọ mi toni yio jẹ "Ogun awitẹlẹ" ti ko gbọdọ pa arọ to ba fi ọkan rẹ sipa ọgbọn. Ẹ gbọ ọrọ mi.

Laipẹyi, Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) daba awọn ohun wọnni to yẹ ki a ṣe ki a to da Aala Ipinlẹ Bini

# "BO-JU-BO-JU, OLORO MBỌ"

ati Ẹsẹ-Ode silẹ, eyini ni Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Ariwa (Ipinlẹ Midwest). Nwọn sọ fun wa ninu ọpọlọpọ aba ti nwọn da pe o yẹ ki a koko ṣe eto ofin ati ilana iṣelu ti yio ṣe itẹwọgba fun gbogbo awọn enia agbegbe Bini ati Ẹsẹ-Ode ki o to dipe a da ipinlẹ wọn silẹ fun wọn. Ẹgbẹ Afẹnifẹre tun sọ pe o yẹ ki awọn Ọba ati Ijoye agbegbe na mọ ipo ati ẹtọ wọn, ati pe ki awọn enia gbogbo nibẹ ni idaniloju nipa ofin p'alafia ati ifọkanbalẹ yio wa fun olukuluku nigbati nwọn ba da ipinlẹ na silẹ.

Ni ti emi, ọgbọn wa ninu aba wọn. O fi han gbangba pe awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre a ma a ronu jinlẹ ki nwọn to dawọle nkan lati ṣe. Mo rope o yẹ ki Ijọba Apapọ yẹ aba wọn wo, ki o si gbiyanju lati mu diẹ ṣẹ ninu wọn fun ire ati alafia Naijiria.

Ṣugbọn ọrọ ti Oloye Festus Okotie-Eboh sọ lori aba na dẹruba mi pupọ. Oloye Okotie-Eboh ko ri ire kan afi ibi ninu gbogbo aba na. Nitootọ, "Ẹṣin ọta ẹni ki i ga." Oloye Okotie-Eboh sọ pe nigbati awọn ba da ipinlẹ na silẹ tan, awọn yio ṣe eto ofin ati ilana ijọba rẹ. O le jẹ pe eyi ṣe deede pelu iwa ati iṣe Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) nitoripe "ṣe e tan ki o to ro o" ni tiwọn, ṣugbọn ki i ṣe ero tabi ọrọ to fun ẹnikẹni ni ifọkanbalẹ, mo si rope Oloye Okotie-Eboh funrarẹ yio gba mi gbọ pe, laisi ikorira ati inunibini, ohun to yẹ ki a kọkọ ṣe nipe ki a mọ iru eto ofin ati ilana iṣelu ti yio ba awọn enia agbegbe na lara mu, ti yio si fun wọn ni ifọkanbalẹ. Eyi ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre wi, ti Oloye Okotie-Eboh fi binu.

O dami loju pe Oloye Okotie-Eboh ko jẹ bẹrẹsi kọ ile tirẹ laikọkọ ronu nipa iru ile ti on fẹ kọ, iye owo ti on lagbara lati fi ko o, ati ibiti o yẹ ki iṣura on wa ninu ile na. O da mi loju pe ko si ile ti Oloye Okotie-Eboh kọ laisi ohun ti awọn oloyinbo npe ni "Plan"—iwe eto kikọ ile.

E ha ti ṣe ti Oloye Okotie-Eboh ati awọn ẹmẹwa rẹ npete lati kọ ilu titun laisi eto? Boya nwọn ko mọ pe o soro lati gbe inu ọkọ ti ọkọ.

Ohun to han si mi ninu ọran na ni pe, awọn Ẹgbẹ Alakukọ fẹ lẹ "igi-ijọgbọn" si Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ-Orun (Midwest). Nwọn fẹ kọ "ile yanrin". Nwọn fẹ loyun hilahilo, ki nwọn si bi ogun, airoju ati airaye bi ti Kongo. Ibajẹpe awọn ara Kongo ṣe eto ofin ati ilana iṣelu ki nwọn to gba ominira, wahala ki ba ti ba aiye nitori wọn; ominira wọn iba jẹ ibukun dipo ẹkun, oṣe ati ipahinkeke.

Ni ti emi, mo fẹ ki a da Agbedemeji Aala Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Ariwa silẹ lọna ti awọn enia ibẹ yio wa ni alafia ati ifọkanbalẹ pẹlu ara wọn. Mo fẹ ki a da ipinlẹ miran silẹ ni Ariwa ati ni Ila-Orun fun iṣọka ati alafia gbogbo enia Naijiria.

Ṣugbọn bi a ko ba mu ikorira ati inunibini kuro ninu ọran oṣelu wa, ti a ko si da awọn ipinlẹ miran silẹ lọna ti "okuta kan ki yio duro le ori ekeji"; bi a ba nfi iwa ati iṣe wa sọ pe ki awọn ẹya kan di "ẹni egun", ẹ jẹ ki a mọ pe "boju-boju, oloro mbọ" ni gbogbo wa nṣe fun iṣọkan Naijiria.

## AKIYESI FUN ONKAWE

Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin o n k a w e ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o maa kọ ọ taara si ile iṣẹ rẹ ni:

**Allied Newspapers Limited,**
**Elephant House**
**214. Broad Street, Lagos**



AGBAYANU
IROHIN ALAGBARA!
NWỌN NTA COMET
RADIO NI G.B.O.!
RADIO TO NLO
BATIRI TABI
TRANSISTỌ NI WỌN
OHUM WỌN
LAGBARA PUPO
NWỌNSI NSỌRỌ
KETEKETE ATIPE.
OWO POKU NI
NWỌN NTA WỌN



**Tetisi awọn irohin ati are oleyimọmọ lori Comet Radio**

K.C.900
O lagbara Transistọ mẹsan
Are-Radio lati orisi ọna mẹta
Apoti rẹ ndan daradara
O ni aworan ẹrọ rẹ lara
£6-10-0

NT 10D
Radio to nlo batiri ati faba
Ti ogubiọrọ enia to mọ nipa radio feran
Apoti to ndan yinrinyinrin
Are-radio lorisi ọna meji
£13-10-0

Awọn oṣiṣẹ-ẹrọ radio G.B.O. ṣe radio
yi lati sọrọ dada nigbagbogbo
Aimọ to ba pẹ o le fẹ ki nwọn o yẹ
radio rẹ wo G.B.O. yio ṣe
eyi fun ọ lowo pọku

Comet
RADIO SETS

G.B.O. TECHNICAL
SERVICE DEPARTMENT

LATI **GBO**

G.B. OLLIVANT (NIGERIA) LTD.

